# OFISI FUN IGBOFINRO FUN IDABOBO ORO AYIKA LABE EKA IJOBA ONIDAJO TI AMERIKA

### ETO AKOKO FUN IGBOFINRO FUN IDABOBO ORO AYIKA

## Akojọpọ

Gege bi itonisona Ipase Aare 14096 se so. "Sisoji Ileri Orile-Ede Wa ti o Nipon fun Igbofinro Idabobo Oro Ayika fun Gbogbo Eniyan" Eka Ijoba Onidajo Orile-Ede Amerika (DOJ) ni lati se itejade Ilana Eto Igbofinro fun Idabobo Oro Ayika ("Eto Imurasile") ti o se igbekale awon afojusun, iran, akitiyan ti o se pataki julo, ati wiwọn esi ati ilosiwaju awon eto fun igbofinro fun idabobo oro ayika. Won ni lati gbe Eto Imurasile yii si ori ayelujara ati ki won fi ranse si Igbimo Ijoba ti o wa fun Eto Ayika ti o Dara, eyi ti o wa labe Alase Ofisi Aare, titi Osu Kewa, odun 2024.

DOJ ti toka si awon eto merin alakoko ti won faramo awon afojusun ti a kojopo si abe yi i:

**Aniyan 1: Bojuto awon ejo ati ilo awon irinse ofin ti eka ijoba l'ona ti o mu ogbon wa.**

a. Bojuto awon ejo ti o le din ailera gbogbo awon eniyan ku ati ewu oro ayika ku
b. Mura si gbogbo orosirisi awọn ona atunṣe ti o wa labe ofin

**Aniyan 2: Ba gbogbo awon ti won nipin ninu re se po, ni ona ti o ni itumo, ki o si je ki won mo nipa DOJ ati ipa ti won n ko nipa igbofinro oro ayika**

a. Foju si ilosiwaju DOJ nipase awon esi ise ti won n se
b. Sekun fifa awon ara ilu mora, ibanise gbogbo awon eniyan, ati bibikita si DOJ ati awon akitiyan won nipa igbofinro fun idabobo oro ayika

**Aniyan 3: Fikun idanileko ati ifowosowopo DOJ nile loko**

a. Tesiwaju nipa idagbasoke eko nipa EJ fun awon osise DOJ
b. Se akitiyan sii lati sowofowopo pelu awọn alabaṣepọ wa ti won wa ni ijoba apapo, ipinle, ibile, ati awon igberiko

**Aniyan 4: Ṣe ayẹwo ati iṣiro igbofinro fun idabobo oro ayika ninu awon akitiyan eka ijoba DOJ, pelu bi won se n ra awon nkan ati ohun-ini**

a. Ri i daju-daju wipe DOJ n ro nipa igbofinro fun idabobo oro ayika ninu isakoso ati isẹ eka ijoba won

## Aaye lati sọ Tẹnu yin ni Gbangba

DOJ fe gbọ ero rẹ lori awọn ibeere pupọ.

1. Kini awon aniyan ati afojusun miran ti DOJ ye ki won kobi ara si ninu Eto won?
2. Bawo ni DOJ se le kara mo akitiyan lati fa awon ara ilu mora ati ibanise gbogbo awon eniyan nipa igbofinro fun idabobo oro ayika?
3. Awon alaye ati eroja wo ni DOJ le se eto fun lati ri daju-daju wipe awon akitiyan won nipa igbofinro fun idabobo oro ayika ye gbogbo awon eniyan?
4. Awon akole ati nkan won lo se koko ti o ye ki DOJ fi si inu eto idanileko awon osise won nipa igbofinro fun idabobo oro ayika?
5. Awon ajo ile-ise wo ni o wa ni agbegbe re, ti o ro wipe DOJ le fi si ori ayelujara listserv ti o wa fun igbofinro fun idabobo oro ayika?

E ni lati fi gbogbo akosile iso tenu yin ranse, ko si gbodo koja ojo **Monday, July 22, 2024**.

E le fi awon akosile isotenu yin ranse ni awon ona yi i:

| | |
|---|---|
| Iwadi ori ayelujara | www.justice.gov/oej |
| Imeeli | oej@usdoj.gov |
| Ifiweranṣẹ | Office of Environmental Justice<br>U.S. DOJ – ENRD<br>P.O. Box 7611<br>Washington, D.C. 20044-7611 |

DOJ jẹ ẹka ijoba apapo opomulero fun igbofinro, won si i tun jẹ oluso abo ti won n pa orile-ede wa mo lowo ewu, ati idabobo awọn ẹtọ gbogbo ara ilu. Lati k'ẹkọ si i, ẹ lọ si, www.justice.gov.